# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ỌRẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 548 THURSDAY MARCH 5, 1964 (2D)


## Ijọba Ibilẹ Eko kọ Abayọri Eto Ikania

EKO—Ni dede agogo mẹta ọsan ijẹta ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ keta Oṣu yi ni awọn ọmọ Ile Igbimọ Aṣofin Ijọba Ibilẹ Eko ṣe ipade wọn Oṣoṣu ti gbogbo awọn ọmọ Ile Igbimọ na si kọ jalẹ lati le fi ara mọ abayọri eto ikania ti o jade ninu ọsẹ ti o kọja yi.

Onirohin wa Ejongboro fi ye wa pe Ọgbẹni Julius Ọdẹku lo da aba na pe ki Ile Igbimọ na o maṣe fara mọ aba yọri eto ikania na, Ọgbẹni Adeniran Ogunsanya si gbe aba na lẹsẹ, gbogbo Ile si fi ara mọ o.

Ọgbẹni Ọdẹku se alaye pe, ojẹ ohun iyalẹnu lati ri wipe gbogbo awọn enia ti ongbe ilu Eko ko to adọta ọkẹ enia (1,000,000).

Ọgbẹni Adeniran Ogunsanya sọ wipe iye ti awọn enia Ipinlẹ Ariwa pe ara wọn jẹ ohun ti oya enia lenu pupọ, o wa rọ gbogbo awọn ọmọ ile igbimọ na lati kọ abayọri iye ti nwọn sọ wipe awọn enia orilẹ-ede yi jẹ.

Lẹhin ti nwọn yiri ọrọ na wo larin ara wọn, gbogbo wọn gba wipe awọn ko faramọ iye ti awọn enia orilẹ-ede yi jẹ.

# ABAYỌRI ETO IKANIA DA YANPỌNYANRIN SILẸ!!

## Awọn Ọmọ Ile-Igbimọ Kọju Ija Si Ara Wọn!

ENUGUN:— Ni ọjọ Isẹgun ti iṣe ọjọ kẹta osu yi ni gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) ninu Ile Igbimọ Aṣofin Apapọ Ijọba Naijiria ati Ile Igbimọ Ijẹba Ipinlẹ Ila Orun ati Iwọ Orun Naijiria ṣe ipade pajawiri kan ninu ile Dokita M. I. Okpara, Alakoso Ijọba Ipinle Ila Orun ati Olori ẹgbẹ Alakukọ ti gbogbo wọn si ṣe ipinnu wipe awọn ko fẹ ba ẹgbẹ Olomi ṣe pọ mọ.

Ninu ipade na, awọn ọmọ ẹgbẹ na sọ wipe ọrọ ti odelẹ nipa abayọri eto ikania yi ki ise ohun kekere bi awọn enia ti se fi oju inu wo ọran na.

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na fi ye oniwe irohin wa wipe, awọn ko ri ba awọn ọmọ ẹgbẹ olomi se ijọba pọ mọ, awọn si ti se tan pẹlu lati ba ẹgbẹ Afẹnifere ma a se ijọba.

Bakanna ẹwẹ, ni agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ na ni awọn ti ṣetan bayi lati ri wipe awọn ko ba ẹgbẹ Ọlọmọkulumbu ṣe Ijọba pọ mọ, ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Awọn si ti ṣe tan bayi lati pe ẹgbẹ Afẹnifẹre, ki awọn jijọ ma a ṣe Ijọba,



Albaji Ahmadu Bello



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

ki iṣe ni Ipinlẹ kan, ṣubọn jakejado orilẹ ede Naijiria ni.

### ỌRAN IJA

Agbọrọsọ awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ na tun ṣe alaye pe, ohun ti o fa a ti awọn fi ṣe ipinnu lati ba aṣepọ awọn pẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ U. P. P. jẹ ọrọ ni ti Oloye Akintọla Olori ẹgbẹ na sọ ni opin ọsẹ ti o kọja yi.

O ni Oloye Akintọla ko kesi awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ki o si mọ ero ọkan awọn ọmọ Ile Igbimọ Ipinlẹ na ki o to sọ fun gbogbo aiye gbọ wipe. "Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria faramọ abayọri eto ikania ti o jade."

O wa bere pe, Bawo ni enia kan ti ṣe le ma a sọrọ fun ara rẹ ni orukọ Ijọba ajọṣepọ lai ko fun awọn yoku rẹ ni ọrọ na gbọ ki o to sọ ọ?"

O ni, awọn ri daju pe iwa "sokesedo" wa larin ajọṣepọ Ijọba Ipinlẹ na, Oloye Akintọla si ti sọ fun gbogbo aiye gbọ pe, Ijẹba Ipinle Iwọ Orun Naijiria faramọ abayọri eto ikania yi, nigbati awọn ko mọ ohunkohun nipa ọrann na.

O ni, ninu ipade ti awọn ṣe ni ọjọ na, ẹgbẹ Alakukọ ati Ijọba Ipinle Iwọ Orun Naijiria tiko Abayọri eto ikania na, awọn ko si faramọ ọ.

A gbọ wipe, laipẹ yi ni ẹgbẹ Alakukọ yio ba aṣepọ ti o wa larin awọn ẹgbẹ U. P.P. jẹ.



Dọkita M. I. Okpara

Nigbati nwọn ro ọran na siwa ti nwọn si tun roo sẹhin, nwọn ri wipe ko tun si ẹgbẹ oṣelu miran ti awọn le ba ṣepọ mọ, bi ko ṣe ẹgbẹ Afẹnifẹre.

### ỌRỌ IYANU

Oniwe irohin wa fi ye wa wipe, wakati mẹrin ni nwọn fi ṣe ipade na, awọn

Minista ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti o wa lati Ipinlẹ Iwọ Orun sọ wipe, awọn ko mọ ohunkohun ninu ọrọ ti Oloye Akintọla sọ lori eto ikania, a ti bi awọn ti gbọ ọrọ na lori ẹro-asọmagbesi.



Dọkita Nnamdi Azikwe

Akọwẹ ẹgbẹ Alakukọ, Ọgbẹni Fred McEwen, sọ pe, "O jẹ ohun iyalẹnu lati le ma a gbọ Ọrọ ti Alhaji Ahmadu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Ariwa ati Olori ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) nsọ, wipe, "Baba nla baba mi ba awọn enia Naijiria jagun, o ṣẹgun o si nṣe alakoso Ijọba awọn enia orilẹ-ede yi.

"Bi baba mi ti nje gaba le awọn enia na lori nigbati o ṣẹgun wọn, bẹni emi na yio ma jọba lori gbogbo awọn enia orilẹ ede yi.

Bẹni emi na yio si maa jọba lori gbogbo awọn enia orilẹ-ede yi titi lailai.

Ọgbẹni McEwen sọ pe bi ẹ fẹ, bi ẹ kọ Ijọba Ipinlẹ Ariwa ni yio ma ṣe "ko so Ijọba orilẹ ede Naijiria

(WO OJU EWE KẸFA)

# IWE SI OLOTU

## A Nfẹ Ẹrọ-Omi Ni Ajegunlẹ

Olotu, Ẹ jọwọ ẹ gba mi laye ninu iwe Irohin nyin Oloyin mọmọ yi lati kesi Ijọba Ipinlẹ Iwọ Orun ati awọn Alamojuto eto Ijọba Ibilẹ Ajegunlẹ lati le pese ẹrọ-Omi m i m u fun awa ti angbe Apapa Ajegunlẹ.

Ilu Ajegunlẹ yi to bi to awọn Ilu miran ti Ijọba yi ti fun un ni ẹrọ.

Ki ẹ si tun gbiyanju lati ri pe ile ifiwe-ranṣẹ (Post Ofiice.) wa tun dara ju bayi lọ. Eyi yi ti kere ju.

Mo dupẹ pupọ lọwọ nyin Olotu.

Emi ni.
E. LAPADE
Ajegunlẹ

## Kini fa Ofin ma mu Siga?

Olotu. Ayọ ni iba jẹ fun mi ti ẹba le gba mi laye ninu iwe irohin nyin yi lati ki awọn ẹlẹgbẹ mi ti ma a saba kọwe jade ninu iwe rohin nyin aladun yi.

Mo fẹ mọ idi re ti nwọn fi se ofin ma mu koko tabi siga nile iya-gbẹ.?

Ko sa si epo petiro nibẹ ti alẹ sọ pe yio gbina.

Mo fẹ ki awọn ti oba mọ idi ofin na ko la ye mi.

Olotu, ẹkọ ọba ko ni sa nyin lẹsẹ o.

Emi ni
L. ANIMASHAUN
Ebute mẹta

## Atọlagbe Ẹ ku Iṣẹ o

Ẹ dakun ẹ gba mi ni aye die ninu iwe nyin oloyin mọmọ lati dupẹ lọwọ ọgbẹni Mọliki A. Atọlagbe fun awọn itan rẹ alarinrin ti o mo nfi da wa laraya ninu iwe Irohin Imọlẹ.

Mo kan saara si ọgbẹni Atọlagbe fun oriki baba wa Elese Ọba ilu Igbaja ti o kọ sinu iwe Irohin Imọle. O ya mi lẹnu fun ọna ti o gba fi kọ oriki, iru oriki Ọba wa to waja ti Ọrẹ wa na kọ ti o si to lẹsẹsẹ, mo ngbadun rẹ.

A si tun nfẹ itan Ilu Igbaja, ọ p ọ l ọ p ọ aladun itan ti o mu ọgbọn lọwọ, arosọ ti odara ki nwọn a mọ ka ninu iwẹ Irehin Imọlẹ.

Otito ọjọ mẹta nisisiyi ti a ti ka ọrọ Ọgbẹni Atọlagbe, mo nbẹ Ọgbẹni Atọlagbe ki o ma gbagbe lati ma ke si Ijọba Ipinlẹ Ariwa ki nwọn le se awọn nkan ti a nfẹ fun wa nilu wa.

A si tun nfẹ Ọgbẹni ba wa sọ itan ilu Igbaja sinu iwe Irohin Imọlẹ. Ki Ijọba Ilẹ ariwa le fun wa ni ominira ti awa na.

Emi ni
KARIMU JASCO
Igbaja.

## A nfẹ Itan ninu iwe nyin

Ẹjọwọ ẹ gba mi ni aye ranpẹ ninu iwe Irohin Imọlẹ lati kesi Olotu tabi Oludari iwe na pe anfẹ itan ninu iwe nyin bo se ẹkan ni ọsọsẹ inu wa yio dun si: Itan jẹ nkan ti ọmọ kọ ni ọgbọn.

Ni ilẹ Yoruba itan je afini mọna to daju nitoripe oje apere fun orisirisi iwa ti awọn ọmọ araiye nhu ẹkọ nla wa ninu itan bẹna ni atun ka tan miran inu o imọ dun de ẹhin.

Mo mọ pe, awọn ojẹgbọn ti ọmọ itan to dara ni siso wa ninu awọn ti nka iwe nyin ni ojojumọ, nwọn yio le sọ itan aladun fun wa.

Gbogbo awọn iwe Yoruba yio ku ni onsẹ itan sinu iwe wọn, nitoripe ọnkọ ọmọde ati agbalagba ni ẹkọ paapa awọn ọm ọ ile-ẹkọ.

Mo dupẹ pupọ fun anfani ti ẹfun mi lati tẹ ọrọ mi jade Ajinde ara ylo mọ je, iwaju ni ọpa ẹbiti nyin yio rẹ si.

Emi ni.
JACOB
Ilawẹ

## E pese Bọọsi Fun Awọn Ọmọ Lewe Ajegunle

Olotu, Iba dun ma mi ti ẹ ba le gba mi laye lati le tẹ iwe mi yi jade ninu iwe Irohin nyin ojojumọ, fun Igbimọ ti mojuto isẹ Bọọsi (L. M. T. S.)

Lati ọjọ pipẹ ni awọn ọmọ lewe larin ilu Eko ati agbegbe miran ma a wọ Bọọsi lọ si ile iwe wọn, eyi ti Igbimọ yi ti pesẹ fun wọn mo fẹ bere, eṣe ti awọn ọmọ ilewe ti o wa ni Ajegunlẹ ko fi mi iru Anifani bayi fun ara wọn. ?

Ohun ti o yẹ ni ki Igbimọ yi tete moju to ọrọ ti mo so yi, lati le pese Bọọsi fun awọn ọmọ ilewe ti ngbe Ajegunlẹ Apapa

Emi ni,
KOLA BALOGUN
Apapa


## AKIYESI

FUN IWADI, ITUMỌ ALA ATI IṢORO RẸ WA TABI KI O KỌWE SI:—WOLI ORIOLO WO AKINDELE ADEAGA COMPOUND ORILE—ILUGUN VIA—IBADAN.



## ỌJA TITUN FUN TITA

1. Iwe Ilana fun Iyanrin, iwosan ati etutu şişe 20/-
2. Iwe Egbogi Ajẹbidan awogbarun 25/-
3. Iwe Afọṣẹ işẹdalẹ Yoruba ati Psalm işẹgun awọn Aje 4/-
4. Gbedegbẹyọ Hausa, Ibo, Oyinbo ati Yoruba 3/-
5. Iwe itumọ Ami Ara ati etutu şişe 4/-6d
6. Iwe itumọ Ala lati ọwọ Josẹfu Alala. 7/6d

Iwe Afinimọna Mẹkka ati awọn orişirişi iwa Yoruba.

Gbiyanju lati bọ ajaga awọn Oso, Ajẹ ati awọn ẹni ibi ile aiye silẹ nipa lilo Iwe Adura, Iwe Afọṣẹ Işẹdalẹ Yoruba ati Psalm Işẹgun Ajẹ.

PẸLU AWỌN ERO IJA RẸ BI:

Holy Candle, Turari işẹgun Ajẹ. Apapọ owo ẹ je 20/- A o fi lilo wọn ranşẹ si ọ pẹlu; ti o ba o le wa fun ara rẹ.

MANAGER:
N2/99, Shittu Street,
Ibadan.



## KERE O! KIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe Ojulowo hauhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS wa na nlo ni Gold Coast (Ankara Ghana)pẹlu, meji rẹ ko si ninu oqgbo orişirişi Egbogi kakiri Ilu Naijiria.




Irohin Kakiri Igboro Ilu

Bẹ na ni ẹwẹ ni igboro Ilu Eko, Irohin ti owa lẹnu gbogbo enia tuọde t'agba ni asiko yi ti nwọn si fi şe ọrọ ati orin larin ara wọn ọpọn Egbogi Jama i olokiki yi ti nwọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dokita Oyinbo ti nwọn nşe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bio ti lagbara to ati o jẹ Ojulowo giriki ati atamata se fun awọn "JẸDIJẸDI" bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹ na ni Iwọn le tun fi ọwọ soya tabi şeileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi Iju, tabi Igẹ şişe, tabi aiko riigbonşẹ dede, Inu rirun nigbakugba ti ni woiwo, Ẹsanri, ẹhin didun. Oju sisan, tabi aiko riran kedere k'odo buruku lara, Osinu Onigbameji ati orişirişi arun miran gbogbo pata "Wipe" nwọn yio ri alafia ni kiakia ti nwọn ba nlo Egbogi LEOPILLS nitoripe o si tun ma tun ẹjẹ şe lara enia nipa sisọ di ọtun p

IŞE IRANT PE ALAFIA L'OGUN ỌRỌ, IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9d)

IYE OWO EGBOGI LEOPILLS: Igo nla şile mẹfa abọ (6/6) pere ni Igo kekere şile mẹta abọ (3/6) pere ni

Bere Ojulowo Egbogi miran fun orişirişi Amọdi ti o ba fẹ ni Şọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palmchurch Street Lagos.
Phone: 22878 Nigeria (Oja ita Faji)

(2) Adedun Chemist
4 W... Street Yaba

# Ọmọ Jaguda Tun Jale ninu Kotu

KAFANCHAN—Ha ṣe gbogbo enia nigbati Alexander Okorie ti awọn Ọlọpa mu wa si kotu fun ẹsun pe orin irinkurin kakiri ilu tun fi ọgbọn yọ owo ṣile mẹfa ni apo Malam Isa bi wọn ti ṣe joko pọ larin kotu.

Gẹrẹ ti Malam Isa ti fura si pe wọn ti yọ owo ṣile mẹfa ni apo on ni oba fi gbe ta ti awọn ọlọpa si bere ti ye ara awọn ero ti opejọ sinu kotu wo.

Bi Alexander ti ri pe awọn ọlọpa ti fẹ ye ara on wo ni oba bu si ẹrin ti osi sile mẹfa na le wọn lọwọ.

Were ni awọn ọlọpa tun fi ẹsun olejija yi kan Alexander kun eyiti oti ba wa tẹlẹ ti osi gba wipe on jẹbi ẹsun na.

Adajọ kotu si sọ ninu ọro rẹ pe, iwa ti o buru ju ni Alexander hu, ati wipe ko yẹ fun lati le ma gbe larin awọn enia.

Adajọ ti ki o lọ fi ẹwọn ọdun meji abọ danra wo.

## Karimu Lu Ọlọpa, O Tun Fa Fila Rẹ Ya!

IBADAN:— Ọrọ di wo-mi-kin wo ọ ni kọtu Adajọ agba nilu Ibadan ni ijẹta nigbati arufin kan Karimu Adisa taku pe ohun ko gbọ iru ẹsun ti awọn ọlọpa fi kan on.

Bi akọwe kotu ti ka ẹsun na seti gbọ Karimu, o wo oke o si wo ilẹ oni "Emi ko gbọ iru ọrọ yi rio"

Onirohin wa fi ye wape, esun ti awọn ọlọpa fi kan Karimu ni pe ọna ọlọpa ibile kan lana sare o si tun fa fila rẹ ya a putuputu.

Awọn ọlọpa sọpe ija yi sẹlẹ ni Oke-ado Ibadan.

Onirohin fi ye wa pe Karimu sọ fun ile ẹjọ pe on ko jẹ bi ẹsun ti wọn fi kan on.

Adajọ wasun gbigbọ ẹjọ na di ọjọ kedogun osu kerin ọdun.

## YẸ IRAWỌ RẸ WO

AQUARIUS (Jan. 20-Feb. 18) Nwọn om uirohin buburu kan wa fun ọ loni. Maṣe binu ojiji ki o ma ba ṣiwahu.

PISCES (Feb. 19-March 20) Itẹlọrun wa fun ọ loni lẹnu iṣẹ ati ninu ile pẹlu.

ARIES (March 20-April 20) O gbọ irohin ijaiya kan loni ti ko ni jẹ ki o pa ọkan pọ si oju kan. Muṣe sọ ireti on.

TAURUS (April 21-May 21) Ojọ oni dara fun ọ lati ṣe ibewo awọn ọrẹ rẹ. Ṣọra pelu owo elowo.

GEMINI (May 22-June 22) Ọran owo kan wa niwaju ti o mu inu rẹ dun loni. Ọjọ oni si tun dara fun ọ lati lọ si Oke Okun.

CANCER (June 22- July 22) Iṣẹ pupọ wa fun ọ lati ṣe loni ṣọra pẹlu iṣẹ aṣeju nitori aisan.

LEO (July 23-Aug. 22) Ilọsiwaju wa fun ọ loni.

VIRGO (Aug. 22-Sept. 22) Gbiyanju lati sunmọ olufẹ rẹ daada loni maṣe jẹki okun ifẹ ti o wa larin yin o ja o.

LIBRA (Sept. 23-Oct. 23) Idaamu diẹ wa fun ọ loni ti ko ni fi ọkan rẹ balẹ.

SCORPIO (Oct. 24-Nov. 22) O ṣe alabapade awọn nia kan ti o ṣe iranlọwọ fun ọ l ni ti o ba kọ nkan ti nwọn fẹ pe ọ si.

SAGITTARIUS (Nov. 23-Dec 21) Ilọsiwaju ati ori re wa fun ọ loni. Maṣe lo asiko rẹ lori ohun ti o ko ṣe ipinnu le lori.

CAPRICORN (Dec. 22-Jan.19) Gbiyanju lati ri awọn ti o yanlodi, ki o si fi oke ṣoro rẹ han wọn. Nibẹ ni iranlọwọ wa fun ọ.

# Iwọ Ha Nlọ Si Mẹkka Ni Ọdun Yi Bi?

"LABEKA ALAHHUMU LABEKA"
MO JẸPE RẸ O, OLUWA MO JẸ IPERẸ

Ẹnikẹni ti o ba fẹ lọ si "MẸKKA" Ilu Mimọ ni ọdun yi gbọdọ ni iwe

"AFINIMỌNA NIPA ISIN HAJI"

LỌWỌ KI OLUWARẸ MA BA ṢINA TABI NA OWO INA KUNA. KI O LE LỌ ALỌBỌ MẸKKA NA DADA

t'Oluwa jọwọ ṣe Isin Haji wa ni eyiti o tọna. Si jọwọ fun wa ni rere ti aiye ati t'ọrun Oluwa wa, ki o sisọ wa ni bi iya nitori IWỌ NI ỌBA alagbara Oluforijin Oluwa gbogbo ẹda patapata" Amin.

## "WAS SALAM"

*AKIYESI* Gbogbo Musulumi Ododo ni oyẹ ki o ni iwe na lọwọ nitori igbati yio ba fẹ lọ si MẸKKA
*Iye Owo 5/6, £3 fun dosini*

MANAGER
N2/99 SHITTU STREET
Ibadan

BERE OJULOWO EGBOGI AWỌN FARANṢE TI NWỌN NPE NI-

# RICHALET

FUN ARUN ẸJẸ ARA ENIA GBOGBO

Eleyi yato patapata si awọn Rọbi-rọbi. Iṣẹ rẹ lara enia si daju fun Iwosan gbogbo Kokoro buburu ti o ba wa ninu 'ẸJẸ ARA' bi Mọnmọnọ




Meji rẹ ko si ni gbogbo awọn Egbogi ti nwọn npe ni TỌNIKI Ẹjẹ ti nwọn si nta kakiri ni owo pọọku adimọwọ tabi ki o lọ nilẹ ko di owo Iyọn ṣe ewọ, awa ki ta awọn egbogi ba wọn yẹn rara tabi ti nwọn npo ta ni ilẹ yi.

Gẹgẹbi awọn Onibara wa ti mọ irufẹ awọn egbogi ba wọn yẹn a ma a ba ọjulowo egbogi atata ti a ranṣẹ fun tita lati awọn ilu Jamani, Faranse ati i awọn Iatambulu s Itali jọ.

Mọ daju pe, bi ẹjẹ ara ko ba mọ daradara awọn amodi tabi ailera wọnyi le se ọ, Lakuregbe, orisirisi Inarun, Oju ṣuṣu tabi didun, Jẹdijẹdi Akọ iba, arun Ẹdọki, Aya - didun pupọ ati Ekuru laya.

Ara riro, lapalapa, Egbo-Ẹsẹ Amodi Apo ile itọ, ẹhin didun tabi ibaradi riro pẹlu Egbogi RISALETI a ma a pa gbogbo kokoro buruku ti o wa ninu ẹjẹ ara rẹ patapata yio si fọ jẹ rẹ mọ toritoni pẹ u.

Ṣa dan igo rẹ kan wo ni iwọ yio si ma a rohin rẹ fun ẹlomiran pẹlu.

Waterloo Medicine Store
8, Palm Church Street Lagos,
Phone: 22878 Nigeria, Ọja (Ita Faji)

NIGERIA MEDICINE STORES
Tinubu Street, Lagos, Phone:- 20278

# E ma a Ka Iwe Irohin Imọlẹ Lojojumọ

# Amẹrika Ṣe Tan Lati Le Kọ Afrika Ni Ẹkọ Itẹsiwaju

ADDIS ABABA:- Irohin kan lati ilu Addis Ababa fi ye wa pe, ilẹ America ti se tan lati le kọ awọn ọmọ ilẹ Africa ni ẹkọ Itẹsiwaju fun ile wọn.

Eyi yi jẹ ọrọ ti o jade lati ẹnu Ọgbẹni J. Wayne Fredericks ẹniti ṣe akọwe kan nile iṣe oludari iṣẹ Itẹsiwaju ilẹ Afrika.

Ọgbẹni Fredericks yi ni agbọ pe o se asiwaju fun awọn Ikọ awọn enia ti o lọ ṣe Ipade kan ni ilu Addis Ababa larin ọsẹ ti o koja yi.

O fi han pe. Olotu Ijọba ilẹ Amerika, Ọlọla Johnson ti ṣetan lati ṣe iranlọwọ fun gbogbo ilẹ Afrika.

Awọn ilẹ Afrika maa gbọdọ jẹ pe wọn jẹ ki ominira ti wọn jẹ rere fun awọn ara ilu wọn laisi Inini lara fun ẹnikẹni.

Ọgbeni Frederick fi han pe, igbimọ awọn minista ilẹ Afrika (O. U. A.) pẹlu Igbimọ ti wa ire ilẹ Afrika (E. C. A) jẹ Ibeji ara wọn ti yio si jẹ opo mulerẹ fun ilẹ Afrika.

O tun fi han wipe Ijọba ilẹ Amerika ti fi owo nla kan silẹ lati le k ọ a w ọ n ọmọ ilẹ Afrika ni ẹkọ imọ ijinlẹ ti yio wulo fun ilẹ wọn ni ọjọ kọjọ. O sọ pe ẹkọ yio bere ni ilu Dakar aipẹ ọjọ. Ọ gbẹni Frederick tun fi han pe Ijọba ilẹ Amerika ti yan on lati lọ se ikede pataki yi nibi pade yi.

Irohin fi ye wa wipe oke amọye pọnun ni ilẹ Amerika le kọ awọn ọmọ ilẹ afrika ẹkọ ilosiwaju.

ki Ọgbẹni Fredrick to pari ọrọ re nibi ipade na a. O fi han gbangba pe ki ori lede kan to ni ilọsiwaju, a gbọdọ ri wipe itẹsiwaju wa wa larin awọn ara wọn ninu ẹkọ ati idagbas ka ara wọn ninu ilera ati le ma bọ awọn ọmọ wọn ni ẹkọ itẹsiwaju.

# ẸJỌ APANIA BẸRE.

ACCRA:- Asiri ọrọ tu jade ninu ile ẹjọ giga Ankara nigbati nwọn bẹrẹ si se ẹjọ ẹniti o fẹ pa Dokita Nkrumah. Ọdaran na ti awọn ọlọpa fi ẹsun kan, jẹ ọmọ ọdun mejilelogun ti o jẹ ọkan ninu awọn ọlọpa ti o sọ ile dokita Nkrumah.

Ọdaran na Seth Nicholas Amatewee ni agbọ pe, nibi ti o ti wa ọna lati yin bọn pa Dokita Nkrumah ni ibọn na ba lọ ba Salisu Darjati ti sọ olori awọn ọlọpa ti o nse ile Dokita Nkrumah ti osi ku bamu bamu.

Ninu ẹsun awọn ọlọpa ti wọn fi kan ọdaran yi nipe, Nicholas Amatewee yi pa a Salifu Darjati ti o si tun fi ẹmi Dokita Nkrumah wu ewu. Nigbati ọga awọn ọlọpa bẹrẹ si ka ọrọ akọsilẹ ti ọdaran na sọ fun awọn ọlọpa ni ati gbọ pe ọdaran na ti sọ pe ọga awọn ọlọpa Samuel Danso Amaning l o se ileri fun on pe ti o n ba le se agbara ati le pa Dokita Nkrumah on yio fun on ni ẹbun ẹgba pọun (£2,000)

O si tun sọ si waju pe ọga ọlọpa na ti fun on ni ogun pọnun saju (£20) Atun gbọ pe Nicholas Amatewee yi tun sọ pe, Dokita Danquah tun se ileri tirẹ pe, on yio ran on lọ si ilu Oyinbo lati le kọ ẹkọ giga. O tun fi han ninu ọrọ rẹ pe ọkan ninu awọn Adajọ Agba ti



Dọkita Kwami Nkrumah
Alakoso Ijọba Ghana

wọn sesẹ da duro Arku Korsha ati alakoso isẹ ọgbin ọgbẹni Krobo Edusei ni ọwọ ninu ọrọ na, ti nwọn siti se Ileri fun on. Sugbọn o sọ ninu ọrọ rẹ pe on koi ti ba ọkankan ninu awọn ti on daruko yi pade Bi wọn ba ti se ẹjọ na si ọo ma gbọ o.

# Akiyesi

Ẹnikẹni ti oba mọ itan awọn Ọba ilẹ Yoruba, iba ṣe eyiti o ti ku ni tabi eyiti oṣi wa laaiye tabi bi nwọn ti ṣe tẹ ilu kọọkan do tabi eyikeyi ninu Itan Iṣẹdalẹ Yoruba, ki oluwarẹ kọ ọ sọwọ.

Ao si tẹ jade fun anfani gbogbo enia. Ẹ maṣe jẹki agbagbe itan Iṣẹdalẹ nitori awọn ọmọ wa.

Ẹ ku iṣẹ o.

OLOTU


# PAYAL

Ojulowo Egbogi kokoro ti o lagbara gidigidi un "Ipare" ti awọn ailera tabi amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu lode ara. Ara, ọwọ tabi ẹsẹ hihun tabi yiyun nigbakugba Alefọ. Egbo ẹsẹ orişirişi tabi ti ọjọ rẹ ti pẹ bi dasin ọ egbo, ekusẹ tabi Lapalapa, Ela, Ara si Akọ Inarun ati orişirişi arun "ARA" miran gbogbo.





Gbiyanju lati dan egbogi titun ti awọn ara Ilu Tata mbulu ṣe ti wọn npe ni "PAYAL" wolarin ọjọ meta iwọ na yio ma rohin rẹ fun awọn ẹlomiran pẹlu Egbogi ipara yi ki ṣe awọn robirobi ti wọn nta kakiri ilu ni owo pọku. Ojulowo egbogi arun ara haunhaun ti ko si şişe ye meji ninu lo jẹ eleyi si yatọ patapata si awọn egerẹmiti adimọwọ ti wọn nta kakiri Igboro ati ni agbereko gbogbo pẹlu. Orisi meji rẹ lo wa. Kekere ati nla.

Bere egbogiajẹbina Paya yi ni şọbu wọnyi.–

Waterloon Medicine Stores
8, Palmchurch Street, Lagos
Phone: 22878 Nigeria, (Ọja Ita Faji)

BI O BA NI
# Iwe—Titẹ
*FUN*
**Lilo nibi iṣẹ rẹ tabi orişirişi iwe itufọ tabi ijade Oku**
*ATI*
**IWE Igbeyawo**

TETE KOWESI ILE—IṢẸ ERỌ—ITẸWE
MODUPE PRINTING PRESS
16, Bamgboṣe Street, P. O. Box 1495
Telephone: 21985. Lagos.
KETEKETE NI ẸRỌ ITẸWE WA NHAN
*OWO PỌKU NI A SI NGBA*
IROHIN KO TO AFOJUBA
*Dan wa wo lẹẹkanṣoṣo ki o si ri iyatọ*

# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No. 548 THURSDAY, MARCH 5, 1964 (2D)


## Akiyesi Pataki Fun Enia Gbogbo

Lẹhinti mo ti ṣe abẹwo kakiri Ilẹ Naijiria ati Ghana, o dabi ẹnipe ọpọlọpọ enia ni nwọn nro wipe Iwe Irohin Imọlẹ ati Iwe Irohin Akintọla ti awọn npe ni Imọlẹ Owurọ ọkan na ni Iwe mejeji.

Eyi ki iṣe bẹ rara asi fẹ fi ye gbogbo enia ki o ye wọn wipe gedegbe ni Iwe Irohin Imọlẹ daduro ko faramọ ẹgbẹ oṣelu kankan ko si ni ohunkohun ṣe pelu Imọlẹ Owurọ.

Iwe Irohin Akintọla ti nwọn ntẹ ni Ibadan ni ongbẹnuṣe fun ẹgbẹ Akintọla Ibadan ni nwọn gbe ntẹ Imọlẹ Owurọ, Eko ni a gbe ntẹ Iwe Irohin Imọlẹ lati ọdun meje (1957) sẹhin.

Ao ṣe ifilọ yi lori Radio fun gbogbo enia lati gbọ, ṣugbọn ẹniti o ba tun fẹ alaye lori ọrọ yi le kọwe tabi ki o wa ri Alakoso Ile Iṣẹ Irohin Imọlẹ ni nọmba

16' BAMGBOṢE STREET,

PHONE 21985, LAGOS.

OLOTU

# AWỌN ỌMỌ YORUBA PARAPỌ DI ỌKANṢOṢO

IBADAN:— Gbogbo ile lo kunṣọṣọ ti ẹsẹ ko si gba ero fun ogunlọgọ ọkẹ aimọye enia, awọn Ọba, Ijoye, Minista, Dọkita, Adajọ, Lọya ati awọn enia sarakisaraki ti nwọn wa si ibi ipade nla kan ti gbogbo awọn ọmọ Yoruba ṣe ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkandinlọgbọn oṣu keji ọdun yi.



Aworan oke yi ni ti awọn Ọba, Ijoye, Minista Adajọ Agba ati kekere, Lọya, Dọkita ọkunrin ati obinrin ti nwọn wa si ipade ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin ni Oke Mapo Ibadan ni ọjọ na.

Nigbati ipade na bẹrẹ ti inu ile ati ode lo kun ti awọn enia ko si ri aye joko.

Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi Ọọni Ọba Ile-Ife lo ṣe alaga ipade na ni deede agogo mọkanla owurọ.

Ninu ipade na Ọba Alaiyeluwa Adesoji Aderẹmi kesi gbogbo awọn ọmọ Yoruba lati le fi imọ ṣọkan ki gbogbo wa o si parapọ gẹgẹbi ọmọ iya kanna.

Ọba Alaiyeluwa na tun ṣe alaye pe, o ti to ọdun meji bayi ti edeaiyede ti bẹ sile larin awọn ọmọ ẹgbẹ Oduduwa lati igbana ni awọn ọba Ipinlẹ yi ti ngbero pe ki awọn le pari edeaiyede na ṣugbọn pabo nigbogbo rẹ nje.

O wa ṣe alaye pe loni, awọn fi idi ẹgbẹ mejeeji na lelẹ, ẹgbẹ ọmọ Oduduwa ati ẹgbẹ ọmọ Yoruba, gbogbo wa si di ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin.

O wa rọ gbogbo awọn enia Ipinlẹ na pe ki nwọn o maṣe fi ọrun awọn ọba bọ ọran ẹgbẹ oṣelu ni Ipinlẹ na.

O ni bi awọn ọba ko ba lọwọ ninu ẹgbẹ oṣelu kankan nwọn o le ṣe iṣẹ wọn laiṣegbe ati laiṣe ojusaju larin awọn enia Ipinlẹ yi.

Ọlọla Adetokunbo Ademọla olori awọn adajọ fun orilẹ ede Naijiria dupẹ lọwọ ọba Alaiyeluwa Adesọji Aderẹmi fun gbogbo ipa ti o sa lati ri i wipe edeaiyede ti o ti wa ni Ipinlẹ yi ko ju bẹ lọ, o si jẹki ifẹ o wa larin awọn ọmọ Yoruba.

Oloye Dọkita Majẹkodunmi kesi gbogbo awọn ọmọ Yoruba lati le gbaruku ti ẹgbẹ na lẹhin, ki asi pa ara wa pọ di ọkan ṣoṣo.

Otun se alaye fun awọn enia na pe, ẹgbẹ ọmọ Ọlọfin yi ki isẹ ẹgbẹ oselu, ẹgbẹ ti yio sọ gbogbo awa ọmọ Yoruba pọdi ọkanṣoṣo ni.

O wa dupẹ lọwọ gbogbo awọn ọba ati Ijoye ti nwọn wa si ibi ipade na ni ọjọ na

Bi oti sọrọ tan, ti osi nlọ joko si aye rẹ ni gbogbo enia ki gbe pe Majẹks! Majẹks!! Majẹks!!!

## Lati Oju Ewe Kini

titi lailai, ẹjẹ mogun baba nla mi ni gbogbo nyin.

AZIKIWE SỌRỌ

Ọlọla Nnamdi Azikiwe Olori Apapọ Ijọba Naijiria ti kesi gbogbo awọn ara ilu pe ki nwọn o dakẹ jẹẹ, ki nwọn o ma si ṣe wulẹ janpata mọ.

Ọlọla Azikiwe ni ọrọ ti awọn enia na nfa mọ ara wọn lọwọ yi jẹ eyi ti o lewu pupọ, o wa rọ gbogbo awọn aṣiwaju ẹgbẹ oṣelu lati dakẹ ọrọ, titi tiabayọri eto na yio fi jade tan ti nwọn o si fi ṣe awọn atunse ti o ba yẹ nipa rẹ,

Alhaji Ahamadu Bello, Alakoso Ijọba Ipinlẹ'Ariwa ti sọ fun gbogbo aiye gbọ wipe Ijọba on ti gba abayori eto ikania ti o jade ni osẹ ti o kọja yi, awọn si ti mura silẹ fun ohunkohun to bale ti idi rẹ jade.

Gbogbo awọn ọmọ ẹgbẹ na ni nwon nṣe ipade abẹlẹ, Onirohin wa kan fi ye wa pe ẹgbẹ Olomi ko ni ba ẹgbẹ Alakukọ ṣe pọ mọ ninu Ile Igbimọ Asofin Apapọ Ijọba Naijiria.

Bikanna ẹwẹ ni ẹgbẹ Alakukọ si ti ṣe ipinnu lati ba aṣepọ wọn pelu ẹgbẹ U. P. P. je ni Ipinlẹ Iwọ Orun Naijiria.

Bi ọran na ba ti tun nlọ, ẹ o ma a gbọ ninu iwe irohin wa.


Printed and Published by Mocupe Printing Press 16, Bamgbose Street, P O Box 1495 Phone 21985
Editor: TUNJI ADEOSUN 4, Kadiri Street (C. M. S. Grammar School) Bariga Yaba Lagos 5 3/64